Yoruba
Yorùbá

# Àwọn ọmọdébìrin àti àwọn Obìnrin àgbàlagbà

## Ohun tí mo ní láti sọ jẹ́ àlàyé pàtàkì fún ọ

Ìwọ ní ẹ̀tọ́ kí á ṣe sí ọ́ pẹ̀lú ọ̀wọ̀
– Kò sí ẹnìkan (láíláí) tí ó ní ẹ̀tọ́ láti wu ìwà ìbàjẹ́ sí ọ, fi ọ́ ṣe yẹ̀yẹ́ tàbí lù ọ́.




Ìwọ ní ẹ̀tọ́ sí àwọn èrò tìrẹ kí o sì sọ wọ́n láìsí ìbẹ̀rù
– Kò sí ẹnìkan tí ó lè sọ fún ọ ohun tí ìwọ yóò rò, ohun tí ìwọ yóò ní ìmọ̀lára rẹ̀ tàbí ẹnití ìwọ yóò lo àkókò pẹ̀lú.

Ìwọ ní ẹ̀tọ́ láti ṣe àkóso àwọn ìṣúná owó rẹ
– Ìwọ ní ẹ̀tọ́ láti fẹ́ láti kàwé, ṣiṣẹ́ àti láti pinnu ohun tí ìwọ yóò ṣe pẹ̀lú owó tí o pa.

Ìwọ ní ẹ̀tọ́ láti pinnu lórí ara rẹ
– Ara rẹ jẹ́ tìrẹ nìkan. Ìwọ lè pinnu ẹnití ó lè fi ọwọ́ kàn ọ́, níbo àti nígbàwo.

Kò sí ọ̀kankan nínú ọkọ rẹ, bàbá rẹ, ọkùnrin àfẹ́sọ́nà rẹ, arakùnrin tàbí ẹ̀gbọ́n tàbí àbúrò bàbá rẹ tí ó lè gba àwọn ẹ̀tọ́ wọ̀nyìí kúrò lọ́wọ́ rẹ.

Ìwọ ní ẹ̀tọ́ láti gbé ayé ní ibití ìwọ ti ní ìmọ̀lára ààbò àti ìdáàbòbò, níbikíbi tí o bá lọ
– Ìwọ kò gbọ́dọ̀ ní láti ní ìmọ̀lára àìní-ìdáàbòbò tàbí bẹ̀rù nínú ilé rẹ, nínú ilé-ìwé rẹ tàbí ní ibi-iṣẹ́ rẹ, ní ilé ìtajà oúnjẹ, nínú ìlú tàbí nínú igbó.

## Ìwọ ní ẹ̀tọ́ láti gbé ayé òmìnira kúrò lọ́wọ́ èyíkéyìí irú ìwà ipá

Bí a kò bá bọ̀wọ̀ fún àwọn ẹ̀tọ́ rẹ, ìwọ ní ẹ̀tọ́ láti gba àtìlẹyìn
Terrafem wà níbí láti ṣe àtìlẹyìn fún ọ àti láti jà fún àwọn ẹ̀tọ́ rẹ àti gbogbo àwọn ẹ̀tọ́ àwọn obìnrin
020-521010